# Itan igbesiaye ṣoki nipa ẹniti Ọlọhun ba sọrọ Musa ọmọ Imran (Ki alaafia maa ba)

Àkojọpọ rẹ wa lati ọwọ:
**Haitham ọmọ Muhammad Sarhan**
Olukọ ni Ile-ẹkọ Al-Haram ni Mossalassi Anabi - tẹlẹ - ati alamojuto ile-ẹkọ Sunnah

https://mahadsunnah.com/

Ki Ọlọhun forijin, ati awọn obi rẹ, ati awọn ti wọn ran-an lọwọ lati gbe iwe yii jade

Òntẹ̀ alakọkọ
Àayè lati tẹẹ wà fun gbogbo Musulumi laiyi nkankan pada ninu nti iwe yii ko sinu.

## Ẹniti Ọlọhun ba sọrọ Musa (ki alaafia maa ba)

**Orukọ rẹ̀ ni :** Musa - itumọ rẹ̀ nipe ẹniti a fa jade lati inu omi.

**Orukọ Baba rẹ̀**: Imran - o wa lati idile Ya'qub ọmọ Ishaq ọmọ Ibrahim, ki alaafia maa ba wọn.

**Orúkọ arákùnrin rẹ̀**: Harun – Wọ́n ran an niṣe lẹ́yìn Musa láti mú àtìlẹ́yìn rẹ̀ lágbára, kí ó sì le jẹ́ alátìlẹ́yìn fun, eleyi waye latara iṣipẹ ti Musa ṣe fún un lọ́dọ̀ Ọlọ́hun.
Yusuf (ki alaafia maa ba a) mú àwọn ọmọ Ísírẹ̀lì - tí í ṣe Ya'qub - wọ ilu Egypt, nígbà tí Yusuf kú, àwọn arale Fáráò fi ìyà to lekoko jẹ wọ́n, ni Ọlọ́hun wa rán Musa àti Harun sí àwọn ọmọ Ísírẹ̀lì àti sí Fáráò ati ijọ rẹ̀, Lẹ́yìn náà ni Ọlọ́hun rán àwọn miran niṣẹ lẹ́yìn àwọn mejeeji tí wọ́n dárúkọ wọn fún wa nínú Al-Qur'an, bii Daud àti Sulaimon, ki alaafia maa ba wọn.

**Orúkọ ọmọ-ọdọ rẹ̀**: Yushau ọmọ Nuuni - ó di Anabi Ọlọ́hun lẹ́yìn ikú Musa àti Harun, ki alaafia maa ba wọn.

**Orukọ olukọ rẹ̀**: Al-Khadiru – wọn yapa ẹnu nipa boya Anabi Ọlọ́hun ni tabi ẹni rere kan.

**Orúkọ adape rẹ̀ àti díẹ̀ lára ohun tí wọ́n fi ṣa a lẹṣa:**
Ẹniti Ọlọ́hun bá sọrọ, Ọlọ́hun ṣa a lẹṣa pẹlu ọla ńlá tí ko ṣe fún ẹlòmíràn, nitoripe Ọlọ́hun bá a sọ̀rọ̀ lórí ilẹ̀ ayé, ìyẹn sì jẹ nitori òye kan ti kosi ẹniti o mọ ọn ayafi Ọlọhun nikanṣoṣo, nitori idi eyi ni a fi npè Musa ni Ẹniti Ọlọ́hun bá sọrọ, nitoripe Ọlọhun pọn le, ti o si ba a sọrọ lati oke sanmọ keje, ni ọrọ taarata laisi iṣipaya tabi agbedemeji eniyan, gẹgẹbi awọn Anabi ati Ojiṣẹ yoku, Anabi Musa jẹ ọkan lara

awọn Anabi onipinnu, ti wọ́n ṣa lẹṣa, (Ó sì jẹ́ ẹni iyì lọ́dọ̀ Ọlọhun) [Al-ahzaab 69] iyẹn nipe: o ni iyì ati ọla ní ọdọ Oluwa rẹ̀, Ọba Alagbara to gbọngbọn, Al-Hasan Al-basiri, ki Ọlọhun kẹ ẹ, sọ pe: (o jẹ ẹniti Ọlọhun ma n gba adura rẹ̀). Ohun ni ẹniti Ọlọhun ṣe e fun ra Rẹ̀. O sọ pe: (Lẹ́yìn náà, o dé ní àkókò tí ó ti wà nínú kádàrá irẹ Musa, Mo sì ṣà ọ́ lẹ́ṣà fún iṣẹ́ Mi) [Tooha: 40-41].

**Orukọ ọta rẹ̀ :** Fáráò – ohun ni Ramasisi keji gẹgẹ bi awọn opitan ṣe n sọ, Amugba lẹgbẹ rẹ̀ ni: Haman (Dájúdájú Fir‘aon, Hāmọ̄n àti àwọn ọmọ ogun àwọn méjèèjì) [Al-Qasas: 8].

**Orukọ tira rẹ̀ :** Taoraat ati Suhuf - wọ́n yapa ẹnu lori pe boya tira meji ọtọọtọ ni wọn tabi orukọ meji fun tira kan.

**Aaye bibi rẹ̀ ati iku rẹ̀ :** wọ́n bi i si ilu Egypt, o sì ku si oke Tuuri.

**Iṣẹ́ rẹ̀ :** Ó ń da ẹran jẹ, o si n tọ́jú wọn.

**Orukọ obirin to re e dagba :** Asiyah – ohun ni iyawo Fáráò.

**Awọn aami Rẹ :** Ohun ni Anabi ti o ni awọn aami ti o pọ julọ lẹyin Anabi wa Muhammad, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a.

**Aaye rẹ̀ :** o wa ni sanmọ kẹfa; gẹgẹ bi o ṣe wà ninu hadeeth ti Anas gba wa, ti awọn alfa (bukhari ati Muslim) si panupọ lee lori.

**Ọpá :** Ó jẹ ẹniti o ma n mu ọpa kaa kiri, ó sì ṣàlàyé idi eleyi bayi pé: (Ọ̀pá mi ni. Mò ń fi rọ̀gbọ̀kú. Mo tún ń fi já ewé fún àwọn àgùtàn mi. Mo sì tún ń lò ó fún àwọn bùkátà mìíràn) [Tooha: 18].

**Ẹ̀sìn Rẹ̀ :** Musa kò mú ẹ̀sìn Júù wá, esin to mu wa ni ẹ̀sìn Islam ni agbọye ti gbogbogbòò, èyí tí ó túmọ̀ sí: (Jijuwọ-jusẹ silẹ fún Ọlọ́hun nìkan ṣoṣo); Ẹsin yi ni ẹsin gbogbo awọn Anabi Ọlọhun lati ori Anabi Nuhu titi de ori Anabi Muhammad, Ọlọhun sọ nipa Anabi Ibrahim pé: (Ànábì ’Ibrọ̄hīm kì í ṣe yẹhudi, kì í ṣe nasọ̄rọ̄, ṣùgbọ́n ó jẹ́ olùdúró-déédé, mùsùlùmí, Kò sì sí nínú àwọn ọ̀ṣẹbọ) [Al-imraan: 67], Ọlọhun sọ nipa Anabi Musa pé: (Ànábì Mūsā sọ pé: “Ẹ̀yin ènìyàn mi, tí ẹ bá jẹ́ ẹni tó gbàgbọ́ nínú Allāhu, Òun náà ni kí ẹ gbáralé tí ẹ bá jẹ́ mùsùlùmí) [Yunus: 84], nitori naa ẹ̀sìn Juu jẹ́ esin irọ ti wọn hun jade lati ara ẹsin ododo ti Anabi Musa mú wá.
Idi ti wọn fi n pe wọn ni Yahudi ni pe: boya nitoripe awọn ọmọ-ẹhin rẹ sọ pe: (Inna hudna ilaik) [Al-A’raf: 156], itumọ rẹ ni: A ronupiwada a si pada, tabi wọn ṣe afiti wọn si Yahuza ti o jẹ akọbi ninu awọn ọmọ Ya'qub, ki alaafia maa ba a.

**Atọkun itan rẹ pẹlu iya rẹ :** Itan naa ko wa ninu Qur'an lẹkunrẹrẹ ayafi ninu Surat Al-Qasas, nibi ọrọ Ọlọhun to sọ pe: (A sì ránṣẹ́ sí ìyá Ànábì Mūsā pé: “Fún un ní ọmú mu) titi de ibi ti Ọlọhun ti sọ pe: (A sì dá a padà sí ọ̀dọ̀ ìyá rẹ̀ nítorí kí ojú rẹ̀ lè tutù fún ìdùnnú àti nítorí kí ó má baà banújẹ́. Àti pé nítorí kí ó lè mọ̀ pé dájúdájú àdéhùn Allāhu, òdodo ni, ṣùgbọ́n ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ wọn ni kò mọ̀) [Al-Qasas: 13].

**Awọn aami rẹ̀ mẹsan-an ni :**

Ọlọhun sọ pe: Dájúdájú A fún Ànábì Mūsā ní àwọn àmì mẹ́sàn-án tó yanjú) [Al-Israai: 101].

Awọn aami naa wá ní ifọsiwẹwẹ ninu Al-Qur'an:

[1] Ọpá : (Nígbà náà, ó ju ọ̀pá rẹ̀ sílẹ̀, ó sì di ejò pọ́nńbélé) [Al-A’raf: 107].

[2] Ọwọ : (Ó tún fa ọwọ́ rẹ̀ yọ, ó sì di funfun gbòlà fún àwọn olùwòran [Al-A’raf: 108].

[3] Ahọ́n : (Tú kókó orí ahọ́n mi, kí wọ́n máa gbọ́ ọ̀rọ̀ mi yé) [Tooha: 27-28], Ọlọhun ṣe koko ori ahọ́n yii fun un nitori ki o le jẹ aami fun un.

[4] Ọna ninu okun : (A sì fi ìmísí ránṣẹ́ sí Ànábì Mūsā pé: “Fi ọ̀pá rẹ na agbami òkun” Ó sì pín sí ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀) [Al-Shu’ara’: 63].

[5-9] Ẹ̀kún omi, àwọn eṣú, àwọn kòkòrò iná, àwọn ọ̀pọ̀lọ́ àti ẹ̀jẹ̀ : (Nítorí náà, A sì fi ẹ̀kún omi, àwọn eṣú, àwọn kòkòrò iná, àwọn ọ̀pọ̀lọ́ àti ẹ̀jẹ̀ ránṣẹ́ sí wọn ní àwọn àmì tí ń tẹ̀léra wọn tó fojú hàn, Ńṣe ni wọ́n tún ṣègbéraga; wọ́n sì jẹ́ ìjọ ẹlẹ́ṣẹ̀) [Al-A’raf: 133].

**Lara awọn adamo rẹ̀**:

Anabi, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a, royin rẹ̀ pe: “Ni alẹ ti wọn gbe mi rin irin-ajo, mo ri ọkunrin kan ti o dudu fẹẹrẹfẹ ni awọ, ó ga, irun rẹ̀ lọ́pọ̀, bi ẹnipe o jẹ ọkan ninu awọn ara idile shanuuha. (Bukhari ati muslim gbabwa)

Aadam: itumọ rẹ ni aláwọ̀ dudu rẹsurẹsu, Al-ja'hd: ẹni tó ní irun to lọpọ, At-tiwaal: ẹniti ó ga looro.

Awọn iroyin wọnyi wà lara awọn iroyin alagbara ati akin, Ọlọhun Ọba sọ lori ahọn ọmọbirin Baba agbalagba pé:

(Dájúdájú ẹni tó dára jùlọ tí o lè gbà síṣẹ́ ni alágbára, olùfọkàntán) [Al-Qasas: 26].
Kosi Anabi Kankan ti wọ́n royin ninu Qur'an pẹlu pé ó di géńdé lẹyin tí ó ti dàgbà dáadáa ayafi Anabi Musa: (Nígbà tí ó dàgbà dáadáa, tí ó di géńdé, A fún un ní ọgbọ́n àti ìmọ̀) [Al-Qasas: 14].

**Lara awọn iwa rẹ** :
[1] Suuru to pọ: "Ki Ọlọhun ṣekẹ fun Musa, wọn ṣe e ni ṣuta pẹlu nkan toju eyi lọ, ṣugbọn ó ṣe suuru." Bukhari ati Muslim lo gba a wa.
[2] Ìmọ̀ to pọ: "Nigba ti Musa n ṣe khutuba fun àwọn ènìyàn rẹ̀ ní ọjọ́ kan, ni ó sọ fún wọn pé: Kò sí ẹni tí ó ní ìmọ̀ jù mí lọ ní ayé". Ahmad lo mu u jade.
[3] Igbarale Ọlọhun (Ó súnmọ́ kí Olúwa mi fọ̀nà tààrà mọ̀ mí) [Al-Qasas: 22].
[4] Ilaakaye ati ara to ni agbara, o si ni afọkantan (Dájúdájú ẹni tó dára jùlọ tí o lè gbà síṣẹ́ ni alágbára, olùfọkàntán [Al-Qasas: 26].
[5] Igbaaya rẹ̀ fẹẹ: (Ànábì Mūsā sọ pé: "Olúwa mi, ṣí ọkàn mi payá fún mi) [Tooha: 25].
[6] Alakinkanju-ọkunrin ati olutaraṣaṣa lati ṣe iṣẹ fun awọn ẹlomiran, (Ó sì bá wọn fún ẹran-ọ̀sìn wọn ní omi mu) [Al-Qasas: 24].
[7] Pipe adehun: (Nígbà tí Mūsā parí àkókò náà) [Al-Qasas: 29].
[8] Ṣiṣe iranlọwọ fún ẹni ti wọn ni lara; gẹgẹ bí ó ti rí nínú ìtàn ẹni tí Musa kàn án ní ẹ̀ṣẹ́, tí ó sì pa a.

[9] Iwa irẹlẹ, fifi ọla awọn ẹlomiran rinlẹ, ati ṣiṣe ojukokoro lati wa mimọ: (nítorí kí o lè kọ́ mi nínú ohun tí Wọ́n fi mọ̀ ọ́ ní ìmọ̀nà) [Al-kahf: 66].
[10] Ẹri ati ọgbọn tí ó lagbara nibi pipeni si ẹsin, ati ilọsiwaju diẹdiẹ ninu ikede ẹsin.
[11] Ipadabọ ati ironupiwada rẹ̀ si ọdọ Ọlọhun: (Ó sọ pé: “Olúwa mi, dájúdájú èmi ti ṣàbòsí sí ẹ̀mí ara mi, Nítorí náà, foríjìn mí) [Al-Qasas: 16].
[12] Sisadi rẹ̀ si ọdọ Ọlọhun ati igbẹkẹle Ọlọhun fun aranse: (Ànábì Mūsā sọ pé: “Rárá, dájúdájú Olúwa mi ń bẹ pẹ̀lú mi, Ó sì máa fi ọ̀nà mọ̀ mí) [Ashua'ra: 62].
[13] Ikẹ ati aanu rẹ̀: (Nítorí náà, jẹ́ kí àwọn ọmọ ’Isrọ̄’īl máa bá wa lọ, Má ṣe fìyà jẹ wọ́n) [Tooha: 47].
[14] Ibinu rẹ̀ ti wọn ba fa ọgba eewọ Ọlọhun ya: (Ànábì Mūsā sì padà sọ́dọ̀ ìjọ rẹ̀ pẹ̀lú ìbínú àti ìbànújẹ́) [Tooha: 86].
[15] Iyara lati mu n kan ṣe: (Ó sì jáde kúrò nínú ìlú pẹ̀lú ìpáyà, tí ó ń retí ẹ̀hónú wọn) [Al-Qasas: 21].
[16] Agbara rẹ̀ nibi fifi ododo hàn: (Dájúdájú èmi náà lérò pé ẹni ìparun ni ọ́, Fir‘aon) [Al-Israa’: 102].
[17] Ifuramọ titobi ojuṣe rẹ̀: (Fún mi ní amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ kan nínú àwọn ará ilé mi, Hārūn, arákùnrin mi, Fi kún mi lọ́wọ́) [Tooha: 29-31]
[18] Irayesa rẹ̀ ni aye ati yiyan ọjọ ikẹyin laayo: (ó sọ pé: “Olúwa mi, dájúdájú èmi bùkátà sí ohun tí O bá sọ̀kalẹ̀ fún mi nínú oore) [Al-Qasas: 24].
[19] Gbigba imọran: (Nítorí náà, jáde kúrò nínú ìlú, dájúdájú èmi wà nínú àwọn onímọ̀ràn rere fún ọ) [Al-Qasas: 20].

[20] Ọlọ́pọ̀lọpọ̀ itiju: “Dájúdájú Anabi Musa jẹ́ olọ́pọ̀lọpọ̀ itiju, tí ó ma n fi ara rẹ̀ pamọ gan, ti awọ ara rẹ̀ kii han sita latara itiju rẹ̀”. (Bukhari ati Muslim lo gba a wa).

**Lara awọn ẹ̀ṣà ijọ rẹ̀**:

[1] Wọ́n rán Anabi Musa si awọn ijọ meji: ijọ awọn Qibiti pẹlu Firiaon, ati ijọ awọn ọmọ Israeli lẹhin iku Firiaon.

[2] Ohun ni igbẹyin ninu awọn Anabi ti Ọlọhun pa awọn ijọ wọn rẹ́, Ọlọhun sọ pe: (Dájúdájú A ti fún Ànábì Mūsā ní Tírà lẹ́yìn ìgbà tí A ti pa àwọn ìjọ àkọ́kọ́ rẹ́) [Al-Qasas: 43], Ibn Kathir – ki Ọlọhun kẹ ẹ - sọ ninu Tafseer rẹ (6/239): (Itumọ rẹ̀ nipé lẹyin tí Ọlọhun sọ Taoraata kalẹ, kò fi iya jẹ ijọ kankan mọ́ lapapọ).

[3] Ohun ni ẹniti awọn ọmọlẹyin rẹ̀ pọju lẹyin Anabi wa, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a, O sọ pe: "Wọ́n gbe nkan dudu nla kan dide si mi, Mo sọ pe: Kini eleyii? Ṣe ijọ mi ni eyi? wọ́n si wipe: Eyi ni Musa ati awọn ijọ rẹ̀". (Bukhari ati Muslim lo gba a wa).

**Ọlọhun dun un ninu O si fọ ọ mọ́:**

Ọlọhun dun un ninu pẹlu ọrọ Rẹ̀ pé: (Wọ́n tún pe Ànábì Mūsā ní òpùrọ́) [Al-Hajj: 44].

Ọlọhun si fọ ọ mọ́ pẹlu ọrọ Rẹ̀ pé: (Ẹ̀yin tí ẹ gbàgbọ́ ní òdodo, ẹ má ṣe dà bí àwọn tó fi ìnira kan Ànábì Mūsā, Allāhu sì ṣàfọ̀mọ́ rẹ̀ nínú ohun tí wọ́n wí, Ó sì jẹ́ ẹni iyì lọ́dọ̀ Allāhu) [Al-Ahzab: 69].

**Itan rẹ̀ ninu Al-Qu'ran**:

Ohun ni Anabi ti wọ́n darukọ rẹ̀ julọ ninu Qur'an, wọ́n darukọ rẹ̀ ni igba 136, ninu awọn surah 34.

Awọn surah tí wọ́n ti darukọ rẹ̀ ní ọpọlọpọ igba ni: Suratul A’raf (igba 21), Suratul-Qasas (igba 18), ati Suratu-Tooha (igba 17).

Idi ti wọn fi sọ itan rẹ̀ leralera nipé: awọn ẹri tí o wà ninu rẹ̀ lagbara, awọn aami si pọ ninu rẹ̀, igberaga, agidi ati itayọ àlà ti o wa lara Firiaon lekoko, Ibnu Saadi - ki Ọlohun kẹ ẹ - sọ ninu tefseer rẹ̀ (oju-iwe 453) pé: (Ọpọlọpọ igba ni Ọlọhun máa n fi Anabi Muhammad, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a, si ẹgbẹ Anabi Musa, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a, bakanaa ni laarin tira awọn mejeji ati ọfin awọn mejeji, nitori pe tira awọn mejeji ló lọ́lá julọ ninu gbogbo awọn tira, ofin awọn mejeji si ni ọfin tí ó pé julọ ninu gbogbo awọn ofin, Anabi awọn mejeji ni ó ga julọ ninu awọn Anabi, ati pé awọn ọmọlẹhin wọn ló pọju ninu awọn onigbagbọ ododo).

**Igbeyawo rẹ̀**:

Musa lo ọdun mẹwa ninu igbesi aye rẹ̀ lori owo ori ọmọbinrin Shuaib, (Ó sọ pé: “Dájúdájú mo fẹ́ fi ọ̀kan nínú àwọn ọmọbìnrin mi méjèèjì wọ̀nyí fún ọ ní aya lórí àdéhùn pé o máa bá mi ṣiṣẹ́ fún ọdún mẹ́jọ, Ṣùgbọ́n tí o bá ṣe é pé ọdún mẹ́wàá, láti ọ̀dọ̀ rẹ nìyẹn) [Al-Qasas: 27] ], Ibnul-Jawzi sọ ninu tira Saydul-Khatir (oju-iwe 40): (Tí kì baa ṣepe Igbeyawo jẹ ọkan ninu awọn nkan tí ó lọ́lá julọ ni, ọ̀pọ̀ ninu asiko awọn Anabi Ọlọhun ibati lọ lori rẹ̀).

**Akopọ itan rẹ ninu Qur'an (ni tito tẹ le ra wọn)**:

[1] Iya rẹ sọ ọ sinu okun ni ọmọ ikoko, o si la, o wa wọ inu aafin Farao.

[2] Ìdàgbà rẹ̀, pípa ọkunrin kan ninu ijọ Farao, ati sisálọ kuro ni Egypt.
[3] Ipade ibukun ni ilu Mọdyana.
[4]Ó lo àkókò naa, ó sì padà sí Egypt.
[5] Wiwa rẹ̀ si afonifoji Mimọ ti orukọ rẹ n jẹ (Tuwa)
[6] Ikọju rẹ pẹlu Farao.
[7] Ìtàn rẹ̀ pẹlu awọn onidan, ati ijade rẹ̀ kuro ni Egypt pẹlu awọn ọmọ Israheel.
[8] Ipade rẹ̀ pẹlu ẹru rere (Khidir).
[9] Itan rẹ pẹlu saamiriyu, ati ijọsin awọn eniyan rẹ fun ọmọ malu.
[10] Itan rẹ̀ pẹlu Qarun.
[11] Itan Maalu.

**Ìtàn èèmọ̀:**

Ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba – sọ pe: "Ẹyin kò lè dà bi arugbobirin inu awọn ọmọ Israila ni?" Wọn si bi i leere, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a; o wá wípé: "Nígbà tí Anabi Musa - ki ikẹ ati ọla o maa baa - mú àwọn ọmọ Ísírẹ̀lì rìn jade kuro ni Egypt, ni wọ́n bá sọnu, ó sì wí pé: Kí ni èyí? Awọn onimimọ inu wọn wá sọ pé: Nigbati Yusuf – ki ikẹ ati ọla o maa baa – n pọkaka iku, o gba adehun lati ọdọ Ọlọhun fun wa pé a kò gbọdọ jade kuro ni Egypt afi ki a gbe egungun rẹ̀ pẹlu wa, o sọ pe: Tani o mọ ibi tí saare rẹ̀ wa? Ó sọ pé: "Arugbobirin kan nínú àwọn ọmọ Ísírẹ̀lì." Ó sì ránṣẹ́ pe e, obìnrin náà sì wá bá a, Ó sọ pe: "Fi ibi ti saare Yusuf wa hàn mí." obìnrin náà sì sọ pé: "o di igba ti o ba fún mi ní ìdájọ́ mi." Ó sọ pé: "Kí ni idajọ rẹ? O sọ pe: Emi yoo wa pẹlu rẹ ninu Alujannah, ṣugbọn o kọ̀ lati fun un ni iyẹn, ni Ọlọ́hun bá fi imisí ranṣẹ si pé kí ó fún un ní ìdájọ́

rẹ̀, nítorí náà, ó bá mú wọn lọ síbi odo kekere kan – ibi omi adagun -ó sì sọ pé: “Ẹ pọn omi yìí ” wọ́n sì pọ́n, ó tun sọ pé: Ẹ gbẹ́ ilẹ, wọ́n sì gbẹ́, wọn wá egungun Yusuf jade, nígbà tí wọ́n sì gbé e dé ori ilẹ̀, wọ́n ba mọ ojú ọ̀nà wọn ti ó mọ́lẹ̀ bí ọ̀sán. (Ibn Hibban ati Al-Hakim ni o gba wa, Al-Albani sọ pe Hadeeth naa ni alaafia).

**Alaye Ibnul-Qayyim nipa awọn Juu:**

Ibnul-Qayyim sọ ninu tira Hidayat al-Hayara (oju-iwe 8): (Ijọ onibinu ni awọn Yahudi, awọn onirọ́, aladapa irọ́, oni jamba, eletekete, elete buruku, olupa awọn Anabi Ọlọhun, olujẹ èèwọ̀ – bi ribaa àti àbẹ̀tẹ́lẹ̀ – awọn ni wọ́n burú jùlọ ní adisọkan, tí wọ́n burú jùlọ nínú ìwà ìkà, ti wọ́n jìnnà sí àánú, ti wọ́n sunmọ ijiya, ìkórìíra ni àṣà wọn, ọ̀tá ati ọtẹ ni iwa wọn, ilé idan, irọ́ ati ete buruku, wọn kii ṣe apọnle kankan fun ẹnikẹni tí ó bá yapa wọn ninu aigbagbọ wọn ati pipe awọn Anabi ni opurọ, wọn kì n ṣọ́ okùn ìbí àti àdéhùn kan fún onígbàgbọ́ òdodo, wọn kì n ṣe ẹtọ tabi aanu fun ẹniti ó bá wà pẹlu wọn, wọn kì n ṣe dọgbadọgba tabi deede pẹlu ẹniti ó bá báwọn ṣe, wọn kì n fi ẹniti o ba wà pẹlu wọn ní ọkàn bale, wọn kì n fun ẹniti o bá báwọn ṣiṣẹ ní imọran, Kàkà bẹ́ẹ̀, ẹni tí ó burú jùlọ nínú wọn ni ẹni tí ó ni laakaye jù, ẹni tí ó gbọ́n jù nínú wọn ni ọdalẹ jù, Ẹniti ọwọ rẹ mọ nínú wọn – ti a kò lè rí iru ẹni bẹẹ nínú wọn – : kì í ṣe Júù ní tootọ, Àwọn juu ni igbaya wọn fún pinpin jùlọ nínú awọn ẹda, ti ilé wọn dúdú jùlọ, ti òórùn àgbàlá wọn buru jùlọ, ti iwa wọn jọ ti ẹranko jùlọ, ègún ni wọ́n fi n kira wọn, erokero ni ipàdé wọn, ìbínú ni aami wọn, ikorira ni awọtẹlẹ wọn).